**Ijọ́ Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu**
**Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nàìjíríà**
**ÌSÌN OMI MÁNNÀ**
**Kókó Àdúrà – ÌWÒSÀN PÍPÉ (10)**

**Ìjẹ́wọ́: Orín Dáfídì 15:1: Olúwa, tani yóò ma ṣe atìpò nínú àgọ́ Rẹ? Tani yóò ma gbé inú òkè mímọ́ Rẹ?**

**Orin Ìyìn àti Ìjọ́sìn**

1. Ọlọ́run ìyanu, àwámárídì, àìnípẹ̀kun, ṣàánú fún mi, ní orúkọ Jésù.
2. Olúwa, ṣàánú fún mi, kí O sì wẹ̀mímọ́ kúrò nínú gbogbo àìlera mi, ní orúkọ Jésù.
3. Bàbá, dáríjì mí fun gbogbo ọ̀rọ̀ búburú àti àwọn ìgbésẹ̀ tímo gbé láìronú jinlẹ̀, ní orúkọ Jésù.
4. Olúwa, jẹ́ kí agbára láti gbọ́ràn sí Ọ lẹ́nu pátápátá àti láti máa gbé ní ọ̀nà Rẹ bàlé mi, ní orúkọ Jésù.
5. Bàbá, gbàmí kí n má ba à mọ̀ Ọ́ ní àmọ̀jù, ní orúkọ Jésù.
6. Bàbá mi, kọ́ mi ní agbára àdúrà, ní orúkọ Jésù.
7. Bàbá mi, kọ́ mi ní àwọn ibùkún àdúrà, ní orúkọ Jésù.
8. Bàbá mi, kọ́ mi ní àwọn agbára áísìkí àdúrà, ní orúkọ Jésù.
9. Olúwa, fọwọ́ ìfẹ́ Rẹ kàn mí, kí O sì yímipadà nípa ore-ọ̀fẹ́ Rẹ, ní orúkọ Jésù.
10. Ìwọ agbára ìfọ́jú t'ẹ̀mí, kú, ní orúkọ Jésù.
11. Ẹ̀yin etí ẹ̀mí mi, ẹ sopọ̀ mọ́ ohùn Ẹ̀mí Mímọ́, ní orúkọ Jésù.
12. Bàbá, fúnmi ní ìwà ìrẹ̀lẹ̀ tòótọ́ àti ìwà tútù t'ẹ̀mí, ní orúkọ Jésù.
13. Jésù Krístì Olúwa, fúnmi ní èrèdí tó dájú àti ìwà funfun ọkàn, ní orúkọ Jésù.

14. Jésù Olúwa, padà wá sínú ọkàn mi báyìí, kí O sì wẹ̀mímọ́ kúrò nínú ohun gbogbo tó n ṣe ibi, ní orúkọ Jésù.
15. Bàbá, kọ́ mi nípa ṣẹ̀ kíkà à àti ṣíṣe àṣàrò nínú ọ̀rọ̀ Rẹ, ní orúkọ Jésù.
16. Ọlọ́run Bàbá, darí mi láti ní òye ìjìnlẹ̀ nípa ìjọba Rẹ, ní orúkọ Jésù.
17. Ọlọ́run Bàbá, darí mi láti ní ìmọ̀ nlá nípa ìfẹ́ Rẹ, ní orúkọ Jésù.
18. Ọlọ́run Bàbá, darí mi láti ní ìmọ̀ èrèdí Rẹ tó hàn kedere, ní orúkọ Jésù.
19. Bàba mi, Bàbá mi, Bàbá mi, fún mi ní iná ọ̀tun láti jà, ní orúkọ Jésù.
20. Agbára Ọlọ́run Ọ̀gá Ògo, ṣíji bòmí, kí O sì sàba sórí ayé mi, ní orúkọ Jésù.
21. Iná agbára tíkò ṣe é takò tàbí rínfín, bàlé mi, ní orúkọ Jésù.